# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. IV. No. 161 SATURDAY, AUGUST 15, 1925. 4d

**Declared Circulation 1,700 Copies Weekly.**



## White's Golden Female Tonic
**(NATIVE)**

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps, Ovarian Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Price 10s. per Bottle.**

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq
41, Offin Road, Lagos
*Packing & Postage 2/6d. extra.*

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elẹjo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Onivòrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹke Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ile, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Işọşọ, Ẹro Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni:—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# NEW GOODS.

---

# Lever Store

## EBUTE METTA.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

ONINI BABA ẸWU.

Ọgbẹni D. L. Oshodi ti 36, Idoluwo *Street, Lagos* ni oriṣiriṣi *Ivory Coat & Trouser Button* (Onini) fun tita kosi aṣọ ti ko ni *button* to yọ. O si ni wabi-wọsi ero-ija *Tailor* (*Tailors Trimmings*) ni tita bakanna; o si nfa'ṣọ ṣe *button* (*Press Coat Buttons*) ki awọn af'aṣọ-dara (*Expert Tailors*) maṣe jafara lati ba ra tiwọn; ọpọku-ọyọku ni ọja meremere wọnyi.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

YE, ỌPA ẸBURUBU TO NṢ'AGBO L'OWO! IGIDA.

Ilẹ rọ ni ọsan *Saturday* ijẹjo nigbati orukuru mimu ti Ijoba *King* mu Eṣugbayi ọmọ-Ọba kuro ni Iga Idunganran lẹhin tiro ti a ti rọ loye tan kẹlu ni. Ọyọ ni ihin kan ni pe a mũ lọ; a si wipe ile ti a jẹ ki o ma gbe ni ile ti Ijọba ti kọ silẹ fun Arẹmọ-Ọba nijelo, ọrọlọpọ iranṣẹ ni a sọ pe a fi si sakãni rẹ, a si sọ pe Alafin gba tọwọ-tẹsẹ; gẹgẹ bi a ti wi l'ọsẹ tokọja, ogun pọnun ni Ijọba yọda fun u lati mã gbà loṣoṣu. Ki Ọlọrun ma ṣai fi mọ bayi fun u.

IGBAGBE KO L'OGUN.

Ọdun ti a darukọ ninu iwe wa ti ọsẹ ti o kọja nipa Ogun Ijẹmọ kiṣe bẹ rara, ọdun na gan ni (*August 8, 1914*,) kiṣe 1908, rara o.

EWO NITI AGOGO AJILU GBỌUNGBỌUN?

Irohin kan ni lati Abẹokuta wa pe ni ọjọ kẹwa oṣu yi niwọn agogo mẹwa orọ ni a dede gbọ Kere o! Ilu yo fi ọdẹ sode, nitorina ẹnikẹni ti a bari ni ago mẹjọ abọ di mẹsan, loru, ọdẹ yio pa a? Nitorina a bẹ ẹnyin Agbagba, ati Igbimọ Ẹgba ki ẹ mura lati ṣe atunṣe fun 're awọn ero ọkọ Lafẹnwa ti magun ni dede agogo mẹjọ abọ di mẹsan alẹ.

ẸHIN RE O, ẸHIN, Ẹ WA WO KU ỌLỌMỌ!

Aba Alufa agba Rev. Supt. D. A. Hughes, ti Ijọ ọmọ Ibilẹ (U.N.A.) kẹdun Iku iya rẹ ti o ṣẹlẹ ni Ebute Mẹta ninu ọsẹ yi.

**Old King's Collegian Society,**
LAGOS.

The Annual Dinner of the Society will be held on or about the 19th of September next, at the Hotel Bonanza.

Tickets ready next week from the
HON. SECRETARY
c/o African Messenger's Office,
Lagos.

Ogun Ikọ, Ogun Ọrin, Adakulẹ, Inukikun, ti obinrin ko ba ri nkan rẹ; aitete loyun, Apeta, Igbẹ Ẹjẹ ati ti Ṣoro, Aipeti, aisan miran, Ori ja-jo-gun, Madarikan, Ẹbi li-le, Adu-Ahọn, Egbo.

Ẹ lọ kesi E. A. OGUNADE, 49, Offin Road, Eko.

ẸNIKEJI,

Aṣọ oke to yanju mbẹ l dọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, *St. John Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

[ *Copyright* ]

# "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

COLONY OF NIGERIA

*AUGUST ASSIZES, 1925.*

A Calendar of Prisoners in His Majesty's Prison, Lagos, to be tried before His Honour Athur Frederick Clarence Webber, Acting Chief Justice of the Colony of Nigeria, at the Assizes to be held at Lagos, on Tuesday, the Fourth day of August, 1925.

Claude Woodruff Duncan, Esq., Sheriff Thomas Stone, Esq., Acting Director of Prisons Thomas Bankole Buko Esq., Acting Chief Registar of the Supreme Court of Nigeria.

Ọdaran kinni—Bogobiri Ọdaran yi ti sa lọ ọna ti jin lati oşu *April 1924*, ti ijọba ko ti ri titi di oni, nitorina ẹjọ rẹ şi sun nọ.

Ọdaran keji—Salawu Kukọyi. Ẹniti awọn ijọba mu wa lati Ẹpẹ fun ẹsun wipe o ji ( £72 ) pọun mejileladọrin owo Yesufu Baruwa kan. Ọdaran yi gba Lọya. Agbẹjọ-ro Ọba ni ẹnyin Juri on fi ẹjọ yi le nyin lọwọ, on ko ba ni ko si ọrọ ninu rẹ, şugbọn on fẹ ki ẹ gba yẹ wo, lẹhin ti wọn wa di rẹ tan, wọn ni ko jẹbi, Adajọ ni ko ma lọ. Salawu Kukọyi bo ba ni Aja Ewulọ ko ki.

Ọdaran kẹta – Lamina. Ẹniti Adajọ Ẹpẹ Ọgbẹni Thomas fi ẹjọ rẹ ranşẹ sibi fun ẹsun wipe o nlo ọbẹ gẹgẹ bi Onişegun Oyinbo, ati pe o si pa Aina kan.

(1) Unlawfully killed one Aina C.C. Sec. 325.

(2) Gave surgical treatment to one Aina in a manner so rash or negligent as to endanger her life. C.C. Sec. 343 (1) (e)

Agbẹjọro Ọba ni awọn ko ba Ọdaran yi rojọ mọ. Adajọ ni ko ma lọ.

Ọdaran kẹrin :—Edward Bickersteth. Eniti Ijọba mu fun ẹsun wipe o fẹ fi eru gba £300 (Ọdunrun pọun) lọwọ Colonial Bank.

"On the 6th day of December 1924, at Lagos, in the Colony of Lagos, with intent to defraud, attempted to obtain from the Colonial Bank, Limited, the sum of £300 by falsely pretending that no part of a sum of £282 standing to his credits in the books of the Colonial Bank, Limited, at Lagos, on the 20th August, 1920, has been paid to him by the said Bank on that date or on any subsequent date. C.C. Secs 419 and 508.

Nigbati Adajọ ri idi ọrọ ọdaran yi, tan, o ni ko lọ si ẹwọn oşu mejidilogun *(18 months hard labour)* pẹlu işẹ Aşegan (Ọdaran yi jẹ ẹni kan ta mọ timọ timọ ọran yi jẹ on ti o ti enia loju, şugbọn ninu ọdun kan ni oşu mẹfa ma pe ki Oluwa ko mu ẹ bọ, ka si ma ri esiko yi anọ ni ọjọ miran.

Ọdaran karun :—Ashiru. Ẹniti Adajọ Ikorodu fi ẹjọ rẹ ranşẹ silẹ yi fun ẹsun wipe o ko kara fun ọdọmọkunrin kan ti oruko rẹ njẹ Mustapha.

(1) Had Canal knowledge of one Mustapha against the order of nature. C.C. Sec 214 (1).

(2) Unlawfully and indecently dealt with Mustapha, a boy of ten years or thereabout. C.C. Sec 216.

Ọdaran yi go to ka fa ni iru, lẹhin ti Adajọ wa idi ọrọ na, o ni on ri pe ko jẹbi ẹsun kinni, nitori ko si iwe Dokita lati fi han, şugbọn o jẹbi ẹsun keji, o ni bi on ba ri wipe iwe Dokita yọju ni on ko ba ju si ọdun mẹrinla şugbọn lori ẹsun keji ko lo si ẹwọn oşu mejidilogun ( *Aşirin biu ba bu*) *18 months hard labour.*

Ẹnyin obi wa, ẹ ma tọju ọmọ nyin tọkọnrin tobinrin lọdọ awọn lagilagi enia ba yi, nigbati okọnrin ko " mu nkan jẹ " fun obinrin mọ, to wa jẹ lọdọ ọkọnrin lo wa ko, Oluwa rere gba wa lọwọ irufẹ awọn enia ba wonyi.

Ọdaran kẹfa Daniel Amikinro—Crown Prosecutor ni awọn ko ba şe ẹjọ mọ ko ma lọ.

Ọdaran keje :—1. Lawani Kasunmu
2. Emanuel Samuel
3. Tijani Ijalẹ

Adajo da awọn odaran keji ati kẹta silẹ ki nwọn ma lo, şugbọn L. K. (Lawani Kasunmu) ko lọ si ẹwọn ọdun mẹta pẹlu işẹ Aşegan *3 years hard labour.*

Aba aya rẹ R mi Taylor kẹdun o ku irọju, Olọrun ko fi ọran mọ bẹ.

*Abọ Assizes re o.*

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATOLUGBOKUN

## THINGS WE WANT TO KNOW.

1. Why are some people pale and sad, and some are happy and rejoicing these are two extreme feelings which seldom take place in a community on the same selfday within a few hours—Sesiai Goma?

2. What is the cause of deadlock in the fish trade market, which is noticeable during the past week?

3. It is a maxim, which reads thus—" The pen is mightier than the sword " in what way does it exemplify itself in our present generation, or the value of present day publicity on it.

4. Why is it necessary for mankind to labour. Is it on account of the Biblical pronouncement of Providence on mankind. And are there any exceptions to this natural and universal law, if so, why?

5. Like begets-Like,—is an axiom. Can Satan rebuke sinners?

6 In solving certain riddles in pictures presented to school children. How is their mental ability gauged by the Teacher?

7. Do girls have better memories than boys, if so, why?

8. What is the marriageable age of an African girl under normal condition?

9. Will any Pastmistress say what are the ingredients in making a delicious dish of palaver sance to an appetizing stranger?

MARY BULL.


# The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

## NEPTUNE
PALE SOAP

## BUGLE
PALE SOAP

## MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 303


It is hereby announced for general information that the majority of the representative members of the families descended from Addo (hitherto commonly referred to as the house of Docemo or the house of Docemo-Oyekan) have elected Ibikunle Akitoye as Eleko in place of Eshugbayi, whose deposition and removal were announced in a Notice dated the 6th day of August, 1925, and published in an *Extraordinary Gazette* dated the 6th day of August, 1925.

It is further notified that His Excellency the Officer Administering the Government has been pleased to sanction the appointment of the said Ibikunle Akitoye as Eleko.

It is further notified that at Government House on the afternoon of Saturday, the 8th day of August, 1925, the said Ibikunle Akitoye was presented by his supporters to His Excellency the Officer Administering the Government, who was pleased to address him in the following terms:—

"IBIKUNLE AKITOYE.

I have had submitted to me a letter to the Resident of the Colony, dated 6th August, 1925, signed by a majority of the persons entitled to elect the Eleko.

2. The letter states that the signatories have elected you, Ibikunle Akitoye, as the right and proper person to succeed Eshugbayi as the Eleko, he having now been deposed, and I am asked to sanction your election as Eleko.

3. I am assured that the signatories are indeed the fit and proper persons to elect the Eleko and that you are in every way a suitable person to hold the position of Eleko.

4. I therefore sanction your election and welcome you here to-day.

5. I shall now report the state of affairs to the Secretary of State and seek his approval to grant you an allowance of £300 per annum from to-day—the date of my sanctioning your election.

6. I wish you to understand that your position as Eleko does not invest you with any ruling function or jurisdiction over any of the inhabitants of Lagos. But as head of the house of Addo, latterly know as the house of Docemo-Oyekan, your influence on the people of Lagos is great indeed.

I look to you confidently to use that influence in two ways. First, to use your utmost endeavours to heal the present disastrous dissensions in Lagos and to be strictly impartial in your dealings with the supporters of Eshugbayi;

Secondly, by your own example to inculcate in the minds of the people a spirit of loyalty to the Government and its orders.

7. So long as you carry out the duties of your high Office in the above spirit so long will you receive the support of the Government."

By His Excellency's Command,
T. S. W. THOMAS,
*Acting Chief Secretary to the Government.*

Chief Secretary's Office,
Lagos, 10th August, 1925.

*The Nigeria Gazette, Extraordinary 10/8/25.*


Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street, begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!

THE

**Nigeria Gazette**

EXTRAORDINARY

*Published by Authority*

**No 76. Lagos, Monday, August 10, 1925 Vol 12**

A fi iwe yi kede fun mimọ gbogbo enia pe awọn ti o pọju ninu awọn ti o duro ni iduro oju awọn ẹbi Ọba ti o ti ilu Ado wa (awọn ti gbogbo enia npe ni Ile Dosunmu tabi Ile Dosunmu-Oyekan titi di isisiyi) ti yan Ibikunle Akitoye bi Eleko dipo Eşugbayi, ẹniti a sọ ti irọloye ati imukuro rẹ ninu Akiyesi kan ti ọjọ 6 oşu *August* ọdun 1925 ti a kọ siwe *Extraordinary Gazette* ti ọjọ 6 oşu *August* 1925-

A tun kede siwaju si i pe inu Adele Gomina dun lati lohun si yiyan Ibikunle Akitoye na ti a darukọ şaju bi Eleko.

A tun kede pẹlu siwaju si i pe ni Ile Gomina ni *Saturday*, ọjọ 8 oşu *August 1925*, awọn ti o şatilẹhin fun Ibikunle Akitoye na ti a darukọ şaju mu u wa han Adele Gomina, ẹniti inu rẹ dun lati ka a sọ awọn ọrọ atẹle wònyi :—

"IBIKUNLE AKITOYE.

A ti fi iwe kan le mi lọwọ, ti a kọ si Balẹ Ilu ni ọjọ 6 oşu *August* ọdun 1925, eyiti awọn ti o pọju ninu awọn enia ti o ni ẹtọ lati yan Eleko ti fi ọwọ wọn si.

2. Iwe na sọ pe awọn ti o fi ọwọ si i na ti yan iwọ Ibikunle Akitoye, bi ẹniti o yẹ, ti o si tọ si lati rọpo Eşugbayi bi Eleko, lẹhin ti a ti rọ on loye, nwọn si nfẹ ki nlohun si yiyan rẹ bi Eleko.

3. A mu ki o dı mi loju pe awọn ti o fi ọwọ si iwe na jẹ awọn ti o yẹ ti o si ni ẹtọ nitotọ lati yan Eleko, ati pe lọna gbogbo li o fi yẹ lati di ipo Eleko na mu.

4. Nitorina mo lohun si yiyan rẹ, mo si fi ayọ gba ọ sihin loni.

5. Emi o rohin nisisiyi fun Akọwe Ijọba ni ilu Gẹsi bi nkan ti ri, ki o si le jọhẹn pẹlu si ati ma san ọdunrun pọun (£300) fun ọ lọdọdun lati oni lọ—Ọjọ ti mo lohun si yiyan rẹ.

6. Mo fẹ ki o ye ọ pe ipo rẹ bi Eleko ko fun ọ li agbara tabi aşẹ kan lori ẹnikẹni ti ngbe Eko yi. Şugbọn gẹgẹbi Olori Ile Ado, ti a wa mọ nisisiyi bi Ile Dosumu-Oyekan, Agbara ti o le sa lori awọn enia Eko ko kere rara.

Mo fi inu tan ọ lati lo agbara yi lọna meji—*Ekini*, ki o lo gbogbo ipa rẹ lati şe atunşe awọ ati rudurudu ti o wa nilẹ nisisiyi li Eko, ki o ma si şe ẹgbe rara ninu gbogbo ibalo rẹ pẹlu, awọn ti o wa bi alatilẹhin fun Eşugbayi.

*Ekeji*, nipa apẹrẹ iwọ papa, ki o kọ awọn en[...] bi a ti şotọ si Ijọba ati si aşẹ ti nwọn ba pa.

7. Niwọnbi o ba ti nşe ojuşe rẹ ni ipo giga [...] a fi ọ si yi, ni iru ọna ti a tọka si yi, Ijọba ki [...] dẹkun ati ma şe atilẹhin fun ọ nigbagbogbo."

Nipa Aşẹ Gomina,

(Sgd.) T. S. W. THOMAS,

*Adele Akọwe Agba ti Ijọba.*

Chief Secretary's Office,
Lagos, 10th August, 1925.

---

Ẹ KUN DE BẸ !

O dun ni gidigidi lati tun gbọ pe Adel[...] Adajọ Agba ko ri si *Motion* ti awọn Lọy[...] tun şe fun dide *Prince* Eşugbayi pada w[...] s'Eko fun ẹjọ rẹ ti a nşe ọpa-alaye rẹ n[...] Kotu Ganran nisisiyi. Ni *Thursday* ọsẹ yi ni Adele Adajọ Agba ta *Motion* yi kulẹ lẹhin igbati awọn Lọya ti şe gudugud[...] meje si ọran na.

A sọ fun ni pe dida iwe-ẹjọ-miran r[...] nipa sẹ ọrọ *Prince* Eşugbayi kana yi di *Wednesday* (Alaruba) ọsẹ to mbọ; Ọwọ a rãn o.

---


— WORTH BUYING —

CHOICE PARISIAN STYLES

FOR THE

VERY SMARTEST WEAR!

:o:

A clever design, exceptionally well shaped crown, trimmed with ICH DIEN feathers. A very superior model indeed for women of good taste. Assorted leading colours.

Also Real Pedal Straw Hats, for Men of Fashion.

Vest Slips—Ties—Half Hose.

All are now in stock at just your own price.

CRUMPSALL SHOW-ROOM.
8, Victoria Road, Lagos.

BE SAFE—BE SURE—BUY GUARANTEED GOODS.

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



# RALEIGH
## THE ALL-STEEL BICYCLE

MILLER BROS. (L'pool) LTD.,
LAGOS.

# EKO AKETE

Eko, Saturday, August 15, 1925.

## ỌRẸ DIẸ, ỌTA DIẸ, OLUWA MA JẸ 'A RĨ!

Bi enia j'ori awun a sọkun fun ohun to ṣẹlẹ ni Igboro ilẹ yi ni *Saturday* Ijẹjọ nigbati ofin Ijọba *King* Alaiyeluwa yọ Prince Eṣugbayi ló kuro ni Eko, ti o si fi di ẹniti Ofin mu kuro ni Iga Idunganran: ẹnikẹni ti o ba wa ni Kotu Ganran ni arọ ọjọ ti a nwi yi, nigbati Ọmọtaku taku wan-nle mọ Gbigbe-Kotu-dide *(Motion)* l'akọkọ lati fi bi aṣẹ Adele Gomina wó, aṣẹ ti o sọ pe ki Prince Eṣugbayi kuro ni Eko ki o to to wakati mẹrinlelogun, oluwarẹ yio gbọ—iyẹn ti oniyẹn ba gbọ Gẹ o, ti ko ba si jinna si Adajọ Agba okodoro-ọrọ ti Ọlọla J. F. C. Webber Adele Adajọ Agba sọ, pe Kotu yi ko ni agbara lati fi bi aṣẹ ti Gomina pa, wo (*This Court has no jurisdiction to set aside an Order made by the Governor*).

Ki a to mọ iwuwo Aṣẹ yi, Ẹ jẹ ki a ṣe apẹrẹ kan: ki o jẹ pe olori ile kan ṣẹ Alagbara Ilu, nibiti a gbe fi ori olori na sọ'lẹ si, ti o si bi, ti o si ni ara ati ibatan nibẹ ja-nrẹrẹ: ki ọrọ na di a-sọti: nigbẹhingbẹhin, ki awọn ẹbi olori na fi ọrọ wọn kọ awọn Oni'lu lọrun: ọgafa, ki a si ti paṣẹ fun irufẹ ẹni bẹ ki o fi ilu silẹ patapata lai ti ni ireti ati tun pada wa, ni kan-nkanṣi mọ, tawo ni ẹ ti ro pe ọkan olori-ile bẹ yio ti ri? Gbẹn-ngbẹn-nẹkẹn, Awuwo bi atẹ-ibanujẹ kan ko ju eyi lọ.

B'o jẹ pe Prince Esugbayi ti ro o jinlẹ ni, lati fi ara rẹ ṣe irubọ—a ko sọpe ki o pa ara rẹ o—ẹla l'ọrọ anisẹ ka jẹ pe o fi gbogbo ọrọ rẹ jẹ oruko ọkọnrin kan oke ọhun, ti o ni on A-suni-Ma-su-Sòkó, ki o si yẹra ni Iga Idunganran, ginni lẹhin titan ọsẹ meji ti awọn ibatan rẹ fun ninu iwe ti nwọn kọ si ni ọjọ kẹwa oṣu ojo (*June*) to kọja, ki o si ṣe ibi-sẹhin-agbo ti ki nṣe ojo, ki o si mu ọna rẹ pọn lọ si bi Oko-Baba, tabi lapakan Ilado nibiti a gbọ pe ilẹ awọn Ọba Eko di wa, dajudaju Ijọba ki yio fi ofin kan nipa fun u, lati kuro nilu ati ni agbegbe rẹ: ṣugbọn awọn "ọrẹ" arẹwọnja nkọ! Awọn ar'owo-ọtẹ-gbadun ko ha fi ake kọ pe b'o ti ma ri lo ma ri, Eṣugbayi ko tẹ koto-ọrọ, iwe-awumọ loriṣiriṣi ko bẹ si jade? Ijọba ko fẹrẹ di iwọlẹ lọwọ awọn alagbara-ma-m'ero wọnyi? oko-ēbu ni ọkan-ko-jọ-kan ninu Iwe-irohin ti o npe ara rẹ ni agbalagba ṣugbọn ti ọrọ inu rẹ fihan bi ẹniti o dagba ilẹkun. ko ha ya ẹnikẹni lẹnu si ọmọ rẹ (*Supplement*) ti o kun fun ọrọ ọmọ-ita ati ede ti ko yẹ ọmọluwabi, ẹnyin ti i gbọ ibiti ọrọ-ēbu-ṣakaṣaka si alaiṣẹ-alairo ni'lu tun nkan ṣe ri?

Igbagbera yi bu-aya to bẹ gẹ ti ariwo "Gidigbo, Gidigbo" fi gba ode kan, nigbati Ọlọla F. M. Baddeley, Adele Gomina si ke "Heya" nkọ, ti o de agbo, ti o si le'wọ ija, o ha gba a ni iṣẹju marun bi, ki gbogbo ilu to gbọ "Gbi i" ni'lẹ, ti ariwo sọ: warawere, awọn apakeji kò ti orin bọ ẹnu pe:—

A la da fẹ̄ só,
A da fẹ̄ só:
A la da fẹ̄ sán
A da fẹ̄ sán:
A la da fẹ̄ tuka,
A da fẹ̄ tuka,

Nigbati ilẹ si rọ́ ni ijẹjọ nkọ, melo ni a ri ninu awọn "Akọni" wa: ọran wiwuwo-tiantian yi ko di ti Ò sin'mọ-de'gbo-ẹru pada? Bi aiye ti ri nũ: ẹni oran ko ba lo npe'ra rẹ l'ọkọnrin Ki Edumare ma ṣai pẹlu Prince Eṣugbayi nibiti o wa loni. Aṣẹ! Ewu ti a f'oju sun nijọ kinni leyi, ti a fi sope adẹbinbọ wiwọ ẹwu aṣoju ki i bi nọ t'orọ: Ẹ ri si ọrọ wa igbanatati ẹ ko ri si, ẹnyin onilakaye enia? Ki Ọlọrun Olodumare ma ṣai fi mọ bayi fun Prince Eṣugbayi.

Otito ni ijinlẹ itumọ owe Gẹsi yi *Save me from my friends* "Gbami lọwo awọn ọrẹ mi": nigbati enia ba sọ pe ki Oluwa gba on lọwo awọn ọrẹ on, itumọ ọrọ bẹ pé ẹgbẹ-gbeje. Ẹnyin Ilu ẹ jẹ ki a ki ara wa lẹkan si, ku Ajalu!

## OHUN GBOGBO KO ŞẸHIN ỌLỌRUN.

ADURA TO YẸ WA NISISIYI NI, K'ỌLỌRUN TU ỌBA WA NINU K'ATUBỌTAN RẸ DARA.

[*Lati ọwọ* KEKERE ILU.]
Si Oniwe-Irohin *Eko Akete*.

Iba o.

Ẹkundebẹ bi oruko omọ-ọlọmọ. Gudugbẹ ti a ti ndu pe ki o ma jẹ ti fọ. O fọ afotan patapata. Abamọ ko ba mọ. A ba kan ma ke ake-isimi ko ran a, a ba si ma sunkun ko tun ba mọ. Ikan şa ni ki a dupẹ fun. Oluwa ko şe ti Ọba wa ni iya ajẹdanu. K'Oluwa ma jẹ ki a tun fi orikunkun da a loro si mọ.

Ki a to mu ẹnu le işẹlẹ ati ojọ Alamisi ni sisọ, o tọ ki a şọpẹ gidigidi lọwọ Ojişẹ Ọlọrun, Ẹni-owọ G. A. Oke, alakoso ijọ ọmọ Ibilẹ, fun iwe olulaja rẹ ti a tẹ sihin ni Satide to kọja. Ẹsẹ kan pere loku. Şugbọn bi Ọlọrun ti fẹ ni. Boya iwe rẹ ko ba şe ire ti ibosi wa atẹnu ọsẹ melokan yi wa ko le şe, a ko le sọ. Amọ a ri i pe "Yoruba" rẹ jina. Ati ile wa ni Ikoyi tirẹ. Ọrọ bi iru eyi ti o tẹ ti a fi wi yi ko le şai fa ẹnikẹni lokan ti o fi rori wo diẹ. Ọrọ rẹ na koi sọnu bi o tilẹ ti jẹ pe Ọba ti a nja fun ti di ẹniti a tigbo ti a si ti mu kuro nilu. Ohun ti o mu wa sọ pe ọrọ rẹ ko yi sọnu, a o sọ ọ nigbati ọrọ ba kan a. Lẹsẹsẹ ni ẹrọ nlọ.

Ọrọ Ọba wa sorikodo biri ni Alamisi to kọja nigbati iwe Adele-Gomina ti a tẹ ni ọse to kọja bọ sode. Jinni-jinni ba t'ẹru t'ọmọ ti ko si ni idi abosi. Gbukẹ ti o fọ silẹ na ya awa tikalawa lẹnu pẹlu pe ara ti nsọrọ fun wa sẹhin a si ti ngbọ irin-abẹlẹ ti awọn to nja Ọba l'ogun nrin. O ya wa l'ẹnu sẹ pẹlu ifura ati akiyesi ti a ti ni sẹhin-sẹhin, şugbọn nigbati Baddeley ti yọ ọwọ rẹ b'ọ ti yọ ni ọjọ nyẹn a ri i pe ko gba etutu mọ bikoşe ki a ko o loju lẹkanna. Ati ko iwe ti bọ sori. A ba ni ki a sare ba awọn ti o kan giri, a ko lẹnu. Ngbọ, ayan ati ajo at'ẹhin-wa şe pabo ni! Ero ti wa nigbana ni pe bi ififalẹ ti wa ni iha ti Ọba wa titi Adele-Gomina ti awọn enia wa ti nwo loju fi yọwọ ija rẹ sode, nwọn iba pe ara wọn jọ ki nwọn yan oju lọ ba Ijọba ki nwọn şe al-mori bi nwọn ti fẹ ki nkanna gbogbo rin. Ọna ti nwọn gba ni lati yẹ aşẹ Adele ti. Awọn Lọya ti nwọn fi işe na fun si pitu han Kotu. Amọ, Ijọba l'a wi. Ohun ti a ta-fa-fa ni Jimọ igba to di Satide ọpakan ni Adajọ agba fi le e pe Kotu ko laşẹ. Ẹ o ri bi alagbara ti şoro gbe şanlẹ! Kini Adajọ bi wọn wo si ni, Agbẹjọro Ijọba ti gba iwe-aşẹ lati fi mu Ọba kuro ni Iga ati kuro ni Ilu, lọwọ Kotu kanna. Awọn ti Ọba wa kẹ ko dakẹ. Awon na si sori-kodo ka nwa ọna ti awọn yio fi şẹ Ijọba lẹse. Oyinbo olori Ọtẹlẹmuyẹ pẹlu olori Ọlọpa (Phillips) ati Ọlọpa kan ni Ijọba ran lọ lati mu Ọba wa gẹgẹ bi a ti gbọ ọrọ na si, nigbati nwọn fi sinu Mọto tan ti nwọn de oju Ọlọbun, biri ni a gbọ pe Mọto yi gbọtun to fi ori le Kereni. Ki a ma da a lọ wonna, Mọto de Yaba ki o to dẹ e diẹ ti awọn Oyinbo fi pada. Iyẹn ni awọn enia wa mi şe kọ nsọ pe Yaba ni nwọn mu u lọ. Ọta, n biti Mọto-ẹlẹru ti duro de wọn pẹlu onjẹ ati ohun ipanu lorişirişi ni a gbọ pe nwọn duro diẹ. Lẹhinna nigbati Mọto awọn Oloye Oluwa, Eletu ati Olumẹgbọn, to gba le ti Ọlọpa nigbati ariwo ti pe mimu lọ ni nwọn nmu Ọba lọ, bajẹ ni Abẹokuta a gbọ pe nwọn duro diẹ fun awọn Oloye lati ki Olowo. Ko si duro mọ, gẹgẹ bi a ti gbọ, titi nwọn fi de Ọyọ. Nibẹ nwọn ba Alafin, ti ẹnikẹni t'Oyinbo-t'Oyinbo ti nduro de Eleko. A gbọ pe Alafin yọ mọ ọ, o fun u ni suru o si tu u ninu.

Awọn Oyinbo ti mura Pẹtẹsi kan nitosi Afin to ni ile lotun-losi fun awọn ẹmẹwa ati Olori. A gbọ pe nigbati Alafin yonda pe ki Ọba wa joko ti on ni Afin, ni a sọ pe Ile tirẹ ti rẹdi ko si dara ki o fi silẹ; şugbọn Ijọba ko fi şe ẹlẹwọn bẹni ko si fi nşe ẹlẹha, nitorina awọn mejeji le ma tọ ara wọn gẹgẹ bi nwọn ba ti fẹ. A gbọ pe Alafin ni eyiun na ko buru. Ara ọrọ itunu ti o sọ fun Ọba wa, eyi ti o wu wa lori ju ni eyi:—Ile l'ọ wa. Yoruba ni ọ, Yoruba ni a; bi a mu ọ lọ si *Zunguru* o gbọ ede wọn? "Ile l'o wa yi, nitorina nşe ni ọ turaka, ọ ma ba wa j'aiye." A gbọ pe ọkan Ọba papa tutu nigbati o ri ifẹ ati aniyan Alafin. Oyinbo ọhun kẹ, nwọn ni o sọ fun pe ti ko ba fi pe o tọwọbọ ibọkubọ kan, ko si nkan; nitori nwọn ko sọ fun on pe iya ni nwọn wa fi jẹ ẹ l'Ọyọ. Nwọn yio sa ipa lati fi nkan gbogbo tẹ ẹ lọrun ti yio fi jẹ pe, iyipada ko şe igbagbe şa ni, ajo ko si le jọ ile, a ba wipe aiye ni o wa jẹ.

Bi Ọba ti nkuro ni Iga ni a le wipe awọn to nja fun u na iwe-ipẹjọ mọlẹ pe ki Gomina mu u pada wa le. Ẹjọ na şiwa nilẹ nisisiyi ti a nkọwe (11. 8. 25).

Eyi ti a fi sọ pe ọrọ *Supt.* Gabriel Oke ko sọnu; idi rẹ ni eyi. Gẹgẹ bi a ti sọ soke Ijọba ti naro wọnin lẹkanna nwọn ko si ni bojuwẹhin mọ. Şugbọn awọn tikalawọn mọ pe bi ko ba si ti ija ti awa ara wa nba arawa ja ati rudurudu ti a ko fi silẹ awọn ko ni ẹjọ nipasẹ ọrọ Eleko. Gbogbo wa l'o mọ bi o ti şe bẹrẹ. Ibi ti ẹtọ ko si Gẹsi ki nşe oju anu fọ. Şugbọn bi nwọn ba ri fitinọ ni'lu ti nwọn si raye diẹ, bi nwọn ti şe fi ti ọşu mẹta atẹhinwa yi woye awọn apakeji, bẹ na ni nwọn le şe. Ogun asọtẹlẹ ki parọ. Iwe Alamisi ti sọ pe nwọn yio ma fun Ọba wa ni owo oşu, Ogun pọnun, niwọn igbati o ba nşe daradara. Eyi ko ni itumọ meji ju pe ki a fi silẹ jẹjẹ ni ijoko rẹ ki a ma tun ko ba mọ. A ti ri i pe pipada rẹ di ọwọ Ọlọrun; şugbọn ẹmi loju. Wipe o şe nkankan paraku to to pa a ni ipo da gbogbo wa li a mọ pe bẹkọ. Şugbọn ija owu ija oro ati iwa agidi ni awa

enia rẹ fi ko ba a, ti a si fi sin i de ipo ti o wa loni. Niwọn igbati o ti daju pe Eleko ko le wa ẹgbẹkan nigbati ẹlomiran wa ni ipo rẹ ko fẹ arijanjiyan mọ lati fihan pe ki nwọn ta kete sira wọn lo dara. Pataki si ni pe Ijọba Oyinbo ki fi Ọba Dudu ti nwọn ba rọ loye silẹ larin ilu kanna, ka tilẹ wipe o le jẹ idunu ẹnikẹni pe ki iru Ọba bẹ tun wa lai yẹra fun sa diẹ.

Awa yọ pe Ọba wa ko ṣe bi opọlọpọ ti fẹ ki o ṣe. Iwa awa ara Eko ki ṣe ohun ti ẹnikan le ku fun. K'Eleko ma jaiye rẹ lọ. Bi ti Eko ko wọ, Eko kọ l'aiye pin. Ifẹ ko si; inukan ko si; irẹpọ ko si. A nfi inuja, a nparaẹni l'ẹpa oro, pọju wa lọ. A dupẹ pe Ijoba ko fi aye silẹ ki Ọba wa ṣ'igba bi awọn oponu ti nfẹ fun u lati idunrun wa.

A torọ lọwọ Ilu pe ki nwọn fi ọwọ wonu, ki nwọn fi ija fun Ọlọrun ja, ki nwọn maṣe ṣe iyọnu pe a nlọ a nbọ nitori awọn adasinilọrun ki nwon ma fe ni ipanpa tabi Ọtẹ kan tun nlọ l'abẹlẹ. Oju ẹda ni ki ngba. Ọba Oke ki gbagbe. Igi buburu ko le so eso rere; ohun ti a fi Ọtẹ gbin ko le duro. Ṣugbọn bi a ba fẹ gbọn ju Ọlọrun lọ a o ṣe idiwọ. K'Ọlọrun tu Ọba Eleko ninu ni ibi to wa, ko fun u ni alafia ati aralile, k'o mu bọ pẹlu ayọ ati alafia laipẹ, ki atubọtan rẹ sunwọn. Ohun gbogbo ko ṣẹhin Oluwa. Rere ni yio kẹhin. Ẹ fọwọ lẹran ki ẹ wo ohun ti Edumare yio ṣe. Ẹmi lo ju. Ẹ ku ifẹ!

KEKERE-ILU.

---

### THE EDITOR'S OBSERVATORY.

#### New Governor of Nigeria.

An item in an issue of *Reuter's Telegrams* of the 12th instant bursts forth the welcome news to the effect that Sir Græme Thomson, K.C.B., Governor of British Guiana, has been appointed Governor of Nigeria by His Majesty the King.

#### Who's Who of the New Governor.

Thomson, Sir Græme, K.C.B.—Born 1875, educated Winchester and New College Oxford, Higher Division Clerk Admiralty, 1900, Assistant Director of Transport 1914, Director of Transport, 1914 Colonial Secretary Ceylon, September 1919, Officer Administering the Government 8-18th January 1920, and March to September. Governor and Commander-in-chief, British Guiana, 1923. Appointed Governor of Nigeria 1925.

#### Lest we forget! Lest we forget!

We offer our meed of praise to Mesdames Abimbola Gibson, Adeyemo Alakija and C. B. Olumuyiwa were Hostesses in the recent Outing of The Nigerian Railway Service Union to which we referred in this column not long ago; the Hostesses made all and sundry feel "At Home" during the happy hours on the Railway Grounds.

#### A New Industrial Home.

The New Boys' Industrial Home at Yaba under the Salvation Army, will be opend at 5 this afternoon by His Excellency, the Officer Administering the Government

#### Aiyedun to come to Ojutaiye.

The Rev. William O. Aiyedun, B.A., of the Northern Provinces we hear, has been offered and has accepted the incumbency of Ebute Ero Church (Anglican).

---


## J. C. VAUGHAN

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o fẹ de awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ri nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Ata, Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwo Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

---

## The "B'yotiri" Mart.

B. O. JOSEPH,

*Licensed Auctioneer, Commission and Estate Agent, Valuer and Appraiser,*

22, Church Street, Lagos, Nigeria.
(Near Carter Bridge).

Undertakes the sale of all kinds of goods also landed properties either by private contract or public auction in any part of Nigeria.

He is also willing to act as commission agent to any of the local firms.

*(Over 21 years' experience in trade.)*

**Cotton, Sundries, Hardware Provisions.**

Prompt rendering of accounts and quick payments.
Moderate Charges.

Sales on Mondays and Thursdays. Commencing at 9 a.m.

*Emergency Excepted*

Patronage is respectfully solicited.

The Mart and Office,
22, Church Street,
Lagos, Nigeria.

*Telegrams*
"Ben. Joseph" Lagos
*Residence.*
35, Richards Lane
Lagos, Nigeria

## ABẸOKUTA.

### IDAHUN SI IWE ARIHIN-R'ỌHUN LORI ỌGBẸNI D. K. ADEOGUN ATI ADUGBO ISALẸ IJEUN.

[ *Lati ọwọ Ẹgba Ọmọ Lişabi.* ]

Si Oni'we-irohin *EKO AKETE.*

ALAGBA,

Ẹ ku atijọ o! Ẹnyin ọkawe *Eko Akete*, ẹ ku lailai o!!

Jẹjẹ ni a joko wa, ti a njẹ, ti a si nmu pẹlu awọn ti Ọlọrun pese fun wa lati oşu *June*, ki Ogboni kan ti o pe ara rẹ ni "Arihin-r'ọhun" to wa tẹ ọwọ rẹ bọ wa l'ẹnu ninu Iwe-irohin kan ti a npe ni *Eko Ọsọsẹ*, eyiti o jade ni ọjọ kini oşu *August*. Ti awa ba wipe a ko ni ge e jẹ rara, yio ro wipe a ko ni ehin l'ẹnu ni; nitorina, awa yio ge e ni ika jẹ diẹ loni: bi o ba tun tẹ ọwọ bọ wa l'ẹnu nigba miran, awa yio tun ge e jẹ, ika rẹ yio si ş'ẹjẹ şoroşoro!

Ko si ohun ti o yẹ Ọgbẹni Adeogun ju idakẹrọrọ rẹ lọ lati ọjọ yi wa. Şugbọn, kini jẹ ki Ọgbẹni Adeogun dakẹ bẹ? Nitori o mọ dajudaju wipe otitọ ni gbogbo ọrọ ti o wa ninu *Eko Akete*. Enia le ni agbara l'ọnakọna nitotọ, şugbọn ki enia to le ni agbara lati sọ imọlẹ di okunkun, yio şe akọ işẹ.

Ẹ jẹ ki a da esi diẹ pada si Ọgbẹni Arihin-r'ọhun yi!

Orukọ ti o njẹ "Arihin-r'ọhun" ko tilẹ ye wa daradara. Tani tilẹ njẹ bẹ? Tabi on ni Dafidi Woli Ariran igbani? (A ko sọ wipe on ni David Kayọde Adeogun o.) Şugbọn, tani njẹ bẹ? Awa ko mọ ẹniti o njẹ Arihin-r'ọhun na. Bi a ba si ri ẹniti o mọ ẹniti o njẹ bẹ, a fi "Ologbo-'jeun" bẹ oluwarẹ, ki o ma şai fi han wa. Tani tilẹ njẹ bẹ sẹ? Tabi on ni Akuwarapa ti o nri aiye ati ọrun ni işẹju kan? Ọlọrun ma jẹ ki a rin ni ọjọ ti ebi npa ọna,—Amin! Ọjọ gbogbo ni ti ole, ọjọ kan ni ti ol'ohun. Nitotọ, o ti mọ Ọgbẹni Adeogun l'ara lati ma sọrọ alufanşa nigbagbogbo, şugbọn, bi o şepe on na mọ wipe ọrọ ti on sọ le ori oku Eman (Ologbe) ni ita gbangba, ni ọjọ kini, yio di oluwa on bayi ni, ki ba ti sọ ọ rara. Dajudaju, Ọgbẹni Adeogun ta şuşu (*stagger*) nigbati o ri ẹrẹkẹ ara rẹ l'aigbe jigin ninu Iwe-irohin *Eko Akete*. Ọrọ na mu u ta gbọngbọn lọ si ọdọ Alake ni iye igba, o tun mu u ranşẹ lọ sọdọ Alufa Delumọ, o si mu u de ọdọ awọn agbagba ilu. Ohun pataki ti o si nsọ ni wipe, nşe ni nwọn korira on nitori on ni owo; nigbati o tun şe, o ni ọrọ ija ile Adekanmbi ni o jẹ ki nwọn ma korira on. Igi ma dạ o! Bi oku ba ni oju l'ọrun nitotọ, Eman (Ologbe) papa yio jẹri wipe awa ko purọ; Ọlọrun kanna, Ẹniti awọn Ẹni-ọwọ Lahanmi ati Delumọ nsin, ti nwọn si nwasu Rẹ nigbagbogbo yio jẹri wipe, ohun ti o sọ si wọn lara loju ọpọlọpọ enia ni awa sọ sinu'iwe wa! A si tun fi Ọlọrun ododo şe ẹlẹri, ti ko ba jẹ otitọ ni o sọ gbogbo ọrọ ti a sọ wipe o sọ si Ọgbẹni D. A. Majẹkodunmi! Ọrọ na ri ẹnikẹni lara ni ọjọ na. Awọn ti a tilẹ nwo bi ọmọ-lẹhin Adeogun kùn si ọrọ na. Ẹnikẹni ti o ba fẹ, ki o tun wa idi ọrọ na, a ko si fẹ ki ẹnikẹni purọ mọ Ọgbẹni Adeogun, ki Ọlọrun ma ba fi iya eke jẹ oluwarẹ; şugbọn ẹniti ko ba fẹ ki Ọlọrun ke ẹmi on kuru gẹgẹ bi ti Eman (Ologbe,) ki oluwarẹ sọ otitọ gan, l'aibu kun, ati l'aibu kuro ninu rẹ!

Iwọ Ọgbẹni Ogunkayọde, njẹ iwọ le fi Ogun orişa baba rẹ (*Cutlass, the god of your father*) bura tabi ki o fi ẹnu kan Bibeli wipe awa purọ ohunkohun mọ ọ? Ọlọrun ti o da eti ha le şe alaigbọran bi, tabi On na ti o si da oju le şe alairiran? Ka *Psalm 94*, ẹsẹ keje titi de ẹsẹ kẹwa.

Nipa ọrọ ilẹ Adekanmbi ti afọju ti o pe ara rẹ ni Arihin-r'ọhun fi ẹnu kan lẹkan, awa ko ri aye lati fi akoko wa şofo lori oku ọrọ yi; şugbọn a o fi ẹnu kan a niba şoki.

Lotọ ni ija ti wa ni ile Adekanmbi; ija nipa ilẹ, ile ati oko (*Land, House and Farm questions.*) Awọn ibatan ara wọn ni o nba ara wọn ja ija yi. Nwọn ko ba Ọgbẹni Adeogun tan lọwọ-lẹsẹ: Arihin-r'ọhun ko le darukọ awọn ẹbi ti o nba ara wọn ja wọnyi, şugbọn awa yio darukọ wọn fun nyin nihin ketekete. Ọgbẹni Salami Ewoşo ni o nba Ọgbẹni Daniel J. Ogunro ati Ọgbẹni Kelani Akitande j'iyan ilẹ, ile ati oko. Apakan ilẹ-ile ni o mu edekoyede yi wa, ki işe gbogbo ile; Salami Ewoşo pe awọn enia meji wọnyi l'ẹjọ si Kotu. Awọn ẹlẹjọ pin are jẹ, nwọn si pi ẹbi jẹ. Salami Ewoşo ni o j'are lati gba ilẹ-ile. Ọgbẹni Ogunro ati Kelani Akitande ni o si j'are lati gba oko: ki işe ẹri ti Ọgbẹni Adeogun jẹ ni o jẹ ki Salami Ewoşo jare ẹjọ ilẹ-ile; bi ẹjọ na ti ri gan ni Ijọba da a yẹn. Şe Ọgbẹni Adeogun wa l'aiye nigbati Ọgbẹni Ewoşo lọ fi owo rẹ pe ẹjọ fun ti oko (*Farm,*) ti o si jẹbi; ọna ikanra da?

Sibẹsibẹ na, ko si ẹniti ko ni obirin to mẹta tabi mẹrin ninu awọn Ọgbẹni Daniel Ogunro ati Kelani Akitande, nwọn ha haya awọn ile tambutambu wọnyẹn lọwọ Arihin-rọhun tabi lọwọ Ọgbẹni Adeogun tabi lọwọ ẹnikẹni bi? Ile baba wọn ni nwọn wa titi di oni-oloni; ọna ikanra ha da?

A fẹ ki ẹnikẹni mọ wipe ohun ọpọlọpọ awọn enia Isalẹ Ijeun ni o nkọ iwe yi, ki işe ọrọ ile Adekanmbi nikan. Ti ko ba si daju, ẹ jẹ ki a bere gbogbo ọrọ mẹwa yi lọwọ Arihin-r'ọhun ati Ọgbẹni Adeogun wo!

1. O ti le ni ọdun kan nisisiyi ti ija ile Adekanmbi ti pari ni Kotu; kini şe ti iwe ko jade şiwaju akoko yi?

2. Njẹ ọrọ ile Adekanmbi lo ha jẹ ki Ọgbẹni Adeogun tako oku Eman (Ologbe) larin ita gbangba, Eman ko sa ba awọn ara ile Adekanmbi tan?

3. Ọrọ ile Adekanmbi lo ha jẹ ki Ọgbẹni Adeogun ma so wipe on ylo jẹ ki nwọn gba Kọla pẹlu Agbada l'ọrun awọn Ẹni-ọwọ Labanmi ati Delumọ bi nwọn ba sin oku Eman l'aisi aṣẹ on ninu re ?

4. Ọrọ ile Adekanmbi lo ha jẹ ki Ọgbẹni Adeogun ma bu Samuel Abatan (bi ẹni wipe o ya owo lọwọ re ri) nitori o fi iṣẹ Ọgbẹni D. A. Majẹkodunmi jẹ fun Alufa Delumo bi ?

5. Ọrọ ile Adekanmbi lo ha jẹ ki Ọgbẹni Adeogun ma sọrọ ileri ati ija si Ọgbẹni D. A. Majekodunmi ni ita gbangba ati ni ile Oluwo Ijeun ati ni ile Balogun Ileun, ani lati ọjọ ti Eman ti ku titi di ọjọ kẹrin oṣu *August* yi ?

6. Ọrọ ile Adekanmbi lo ha jẹ ki gbogbo awọn Janma Imale Ijeun binu si Ọgbẹni Adeogun nigbati nwọn so wipe o ta abuku fun gbogbo wọn nipa ọrọ Sunmonu Awuruku ?

7. Awọn ara ile Adekanmbi lo ha fi aṣẹ fun gbogbo Janma Imale Ileun wipe nwọn ko gbọdọ lọ si Inoja Ileku iya Adeogun tabi Kelani Balogun wọn lo fun wọn ni aṣẹ ?

Ojo mẹwa ni Ọgbẹni Sunmonu Lifowope, Balogun Ijeun fi ṣe wahala ki nwọn to pari ija larin Ọgbẹni Adeogun ati awọn Janma Imale Ijeun ni *Tuesday* ọjọ kẹrin oṣu *August* yi ; Ọgbẹni Adeogun si fi ẹnu ara rẹ so wipe awọn Imale ko t'ẹṣẹ bo ile on lati nkan bi oṣu mẹfa : nje awọn ara ile Adekanmbi lo ha fi aṣẹ fun gbogbo Janma Imale wipe nwọn ko gbọdọ t'ẹṣẹ bo ile Adeogun ?

9. Ọrọ Ile Adekanmbi ko lo ha jẹki Ọgbẹni Adeogun sọ ni ile Oluwo Ijeun pe bi a ba ti mu awọn Ologboni, Ologun, ati awọn Paṭakoyi kuro, pauti (*Rubbish*) ni gbogbo awọn ti o tun ku ni Ijeun ? Awọn Imale ro eyi na mọ ẹjọ ni ileBalogun Ijeun.

10. Nje ọrọ Ile Adekanmbi lo jẹki Ọgbẹni Alaka ibatan (*Cousin*) Ọgbẹni Adeogun pupa ti nwọn ngbe ile kanna di oni oloni mā wijọ (*complain*) kiri adugbo wipe iṣẹ ọkẹ marun (£150) ti Ogbeni Adeogun ba on ṣe ọna re ni ṣọbu Lagos Store ni Ṣọpọn, awọn Igo ọti (*Bottles of Dry Gin*) ti Ọgbẹni Adeogun gba lọwọ on pọju ore ti o ṣe fun on lo, ati wipe Ọgbẹni Tanimọwo Onikafinta ati Mich Abiodun onişọbu Ṣapon mọ dajudaju nipa awọn ọti wọnyi ? Awa ko ngbe ile awọn deogun ati Alaka, Ọgbẹni Adeogun ko si gba ọti lọwọ Alaka loju wa. Nitorina bi ọro ti ọti ba jẹ eke, a jẹ pe Alaka lo ṣeke na, bi o ba si jẹ otitọ Alaka lo sọ, ṣugbọn ẹniti o ba nsọ otitọ yio ma roki ninu awọn ẹlẹri awọn ẹyini ni awọn Ọgbẹni Tanimọwo ati Mich Abiodun.

A duro bayi loni, bi Ọgbẹni Adeogun ki ba fi oro rẹ gba ode titi ọsẹ ti mbọ, a o pari ọrọ wa ngbara Ọlọrun.

*Koi li pari.*

Emi ni ti nyin ntotọ,

ẸGBA ỌMỌ LIṢABI

## FALANA Ẹ GBỌ TI ARA YIN, TI ARA ẸNI L'A NGBỌ.

Si Oni'we Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ foji o,

A ri ka ninu iwe-irohin *Eko Ọsọsẹ* ti ọsẹ t'okọ *25th July* 1925, lati ọwọ *Akirimanu* pe awọn Ahmadia tun gbe iṣe won de nipa ala ti ọkan ninu ijọ awọn la eyiti *Akirimanu* fi we ala ti Anọbi Yesufu ati pe ọkunrin Ahmadia yi, ẹniti o pe ... Woli ọsangangan, sun orun isun kusun ni o jẹ ki ... ri iran ti o ri ki a ma fa gun lọ mọ, bi o tilẹ jẹ pe orun isunkusun ni gẹ ẹ bi *Akirimanu* ti wi, awọn gba iran na gbọ fun ikilọ daradara fun ilosiwaju ẹsin (*Religion*) ati ironupiwada ẹṣẹ.

Papa nipa ti Anọbi Yesufu (*Alai Salam*) ti *Akirimanu* fi ẹnu kọn, tani o le sọ pe inu awọn arakonrin rẹ ko tajẹ ati pe yẹyẹ kọ ni nwọn fi ... bi iwa ọpọlọpọ enia ni Eko loni yi, nigbati o ... iran ala tirẹ fun awọn obi ati awọn arakonrin rẹ ! Nitorina gẹgẹ bi iran ala ti Anọbi Yesufu ti tọ ... si awọn obi ati awọn arakọnrin rẹ bẹna gan ni ti ọkonrin ijọ Ahmadia yi si awọn Jamat rẹ ri nikanṣoṣo ; emi ko ro pe o tọ si ijọ miran ki o dasi i ati lati ma ṣe yẹyẹ ai ko ro'nu bi ko ṣe awọn alai ko ni iṣẹ ṣe ati awọn oni'fun kan bi ejo.

A mọ dajudaju pe okọnrin Ahmadia yi ki nṣe Anọbi rara ati pe on papa ko si pe ara rẹ bẹ tabi Woli ọsangangan bi ọpọlọpọ enia ti nwi, ṣugbọn nwọn gbagbe pe Ọlọrun a ma fi ami rẹ han awọn olododo ati awọn talaka ni oniruru ọna fun ironupiwada ẹṣẹ awọn ara ilu, ijo, ara (*Family*) pataki awọn alufa nigbati ijafara ilosiwaju ẹsin ba fẹ de si wọn, nitoripe alanu ni Ọlọrun. Sibẹsibẹ ọpọlọpọ enia si wa ti nwọn ki nro'nu jinlẹ ki wọn wo gẹgẹ bi nkan ti nlọ ki nwọn to jalu. Papa akoko ti a wa nisisiyi kuro pe ki a jalu ọrọ li ai ko woye rẹ finifini, ki a fi iye si ara ki a si ye yẹyẹ alusi ṣe ati pe ki a si ye gbe era ti ko l'ọmọ ninu ṣere. Iran ala ti ọkunrin Ahmadia yi ri kọ lọ bi ẹnyin ara Eko ti nta Kayiti rẹ kiri ilu.

A dupẹ lowọ Baba Olodumare pe awọn alagba ijọ Ahmadia na ti nwọn daruko pe iran ala na bawi ko gbe ẹriti o l'ala na lọ siwaju baba ẹgbẹ (*Chief Magistrate*) ki konko ba le ru u gẹgẹ bi imọran *Akirimanu* ṣugbon on papa gbagbe pe otitọ ọrọ ni Anọbi Yisa (*Jesu*) sọ fun awọn Yẹwudi (*Jews*) ki nwon to gbe duro niwaju baba-ẹgbẹ (*Pontius Pilate*). Ewo lo tun ku ? Aiye ma kọ otitọ.

Mo ranti niwon ọdun meje tabi mẹjọ sẹhin nigbati ọkunrin Ọdẹ kan ti Ibadan wa si Eko yi pe on ri Mọlaika (*Angel*) kan ati pe Ogun (*Remedy*) fun ikilọ ati ifison Mọlaika na ni pe ki gbogbo ilu gbaradi ki won ṣe ironupiwada fun imukuro ẹṣẹ nitoripe ago ẹṣẹ enia ti kun a kun wọ silẹ bi bẹ kọ ajakalẹ arun yio sọkalẹ si aiye ...

lọpọ enia yio si ku ati lẹhin ọdun diẹ si wahala ati jẹ ati mu yio tun wa ni ibi gbogbo. Jọwọ sọ fun mi iwọ oni yẹyẹ! Kilı ohun ti ara Eko ṣe si ikilọ ati ifisun nlanla yi o? Kaka ki a ro'nu jinlẹ ki a si gba ọkunrin Ọdẹ na gbọ nṣe kọ ni nwọn fi nkọrin kiri pe Ọdẹ kan ti Oke Ibadan wa purọ l'Eko pe on ri Mọlaika ti nwọn si fi nṣe onıruru ẹlẹya ti nwọn si wipe ori Ọdẹ na kope. Iran na ṣẹ tabi ko ṣẹ? Evi ko to ilana ati ẹkọ nla fun gbogbo ara Eko pe bi a ba gbọ ọrọ iyanu kan tabi bi ẹnikan ba ni on ri iran kan ki a ro'nu jinlẹ daradara si ọtun ati si osi ki a si fi yẹyẹ ṣiṣe silẹ. "Ẹ ye yẹyẹ ṣe yẹyẹ ni npa ni, ẹ ye eke ṣe eke ni npani."

Papa e wo lo to ẹkun ati yẹyẹ ṣiṣe ẹnyin agbonrandun? Ẹniti o l'ala yi ninu ijọ Ahmadia ni o wa, ko sọ nikọkọ afi nigbangba pe iran ala na ba ijọ miran wi, ni Kristẹni o tabi Imale, bikoṣe ijọ ti on papa wa ati pe awọn ti iran na bawi l'ọmọde ati l'agbalagba ninu ijọ Ahmadia na tumọ rẹ ki nṣe ohun ti o buru bikoṣe fun itaji fun ilọsiwaju ẹsin. Ẹ jọwọ a bẹ nyin gidigidi ẹnyin a ri jẹ ninu idaru ẹ gbọ t'aranyin falanọ ọrọ yi ko kan nyin lọwọ ko kan nyin l'ẹsẹ rara ẹnyin eleti ọfẹ bikoṣe ọrọ larin baba ati ọmọ.

Iyoku di'regbe, ki a tilẹ ni riro ala na mu edeko-yede wa si arin Jamat Ahamadia nipasẹ awọn diẹ ti arakunrin ti o rọ ala na darukọ ni ọjọ Jimọ (*Friday*) osẹ diẹ sẹhin *17th July 1925*, e wo ni ti nyin ẹnyin Pakokọ, ẹ ma yin kun, ẹnyin ara Eko ati mọ pe ọrọ olọrọ ni ẹ nyin kun. O to gẹ wayi ẹ lọ tẹ igasi nyin bọ awọ.

[-]Idi ọrọ mi re o. Ẹnyin Jamat Ahamadia Imọran mi ni pe ki ẹ maṣe fi eti si fere ifọnkulọn awọn ara Eko nipa ọrọ ala yi ki ẹ mọ dajudaju pe era ko fẹ poroporo de 'nu.

*Asalat ala Nọbiu.*

IYANDA.

---

## IROHIN MINNA.

[ Latilọwọ PROFESSOR BUBUYEH. ]

### ỌMỌ TITUN ALEJO AIYE.

Inu wa dun pupọ a si ba ọrẹ wa Mr. Y. E. Jackson yọ, ara Ibini ọmọ arokun tayo, fun ọmọkunrin titun jantojanto, ti Iyawo rẹ Janet bi fun pẹlu alafia ni ọjọ Jimọ ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu *July*, 31/7/25, ni agogo mẹrin-abọ aṣalẹ 4.30. p.m. ki Ọlọrun ko da ọmọ na si fun awọn obi rẹ *Amin.* Ko si ṣınu awọn ti koi ti ni, ki wọn ko l'ọwọ ṣosun, ki gbogbo wa le jọ jumọ ma jọ kulunbu yẹyẹ, yẹyẹ kulunbu; a tun ki ọmọ titun alejo aiye, kabọ o.

### PIRI L'OLONGO NJI A KI BA OKUNRUN ẸIYẸ LORI ITẸ.

A ki ọrẹ wa Mr. L. W. Bailey, *Post Master*, Minna ati Iyawo rẹ, fun amodi otutu ferẹ (*Light Fever*) to fẹ si ọkunrin na, ọpẹlẹngẹ awẹlẹwa, Ọwa wa fohun ṣakin ọkunrin, ajinde ara a ma jẹ yin o.

### ỌLỌRUN KO GBA WA LỌWỌ ABIKU AGBA AMIN

A ba ọrẹ wa kẹdun Mr. Eman Ọjaṣigun ọmọ alarẹ, olowo pa ṣile laro ti ọmọ rẹ obirin Wundia ti o ṣe alaisi ni *Monday*, ogunjọ oṣu *July* 20/7/25. Ọlọrun ko dẹlẹ fun, ko si tu awọn obi rẹ ninu *Amin.*

### IJỌ ỌMỌ IBILẸ U.N.A. CHURCH IRANWỌ ALLA

Ọjọ keji oṣu *August*, 2/8/25, gẹgẹ bi eto wọn iwasu ti oloyinbo o tun yi de, gẹgẹ bi a ti gbọ ne Mr. L. W. Bailey ni wọn yan ko ṣe Iwasu ọjọ na, ṣugbọn ara arakunrin na ko le, otutu ferẹ fẹ si, ṣugbọn (*ever r e a d y President*) Marcus Thomas, alakikanju ọkunrin o ti gan iwasu na lairotẹlẹ, o yan ọrọ iwasu rẹ lati inu Ihin Rere Matthew ori karun ẹsẹ kẹrindinlogun "*Let your Light so shine before men*" "Ẹ jẹ ki imọlẹ yin ki o mọlẹ tobẹ niwaju awọn enia" &c. ẹnu jagun ti dun bi oyin, o si nwasu gẹsi laiṣi iwe wo (*Extempore*) gẹgẹ bi awọn oniwasu Ṣọṣi Wesileni (*Wesleyan*) lẹhin na e tun pa ohun da si Yoruba, Ọ̀gboni na ṣoro rọti ninu Bibeli Mimọ nigbati mo bere pe kini o ti ṣe dun lẹnu rẹ bayi tabi o ti gba oye Bibeli ni (LTH) a ṣe jagun ko de koto ọrọ iṣẹ *Teacher* Ologundudu (*now Rev*) ni nkan ọgbọn ọdun *30 years past* lo ndun lori rẹ a dupẹ lọwọ awọn *Teacher* atijọ ti wọn fi Iwe Mimọ (*Holy Bible*) kọ awọn enia.

A o si bẹ awọn *Teacher* ti isisiyi ki wọn jọwọ ki wọn ma fi Iwe Mimọ bẹ kọ awọn ọmọ wa, ki wọn ma joko ti *a cat and a rat, a fat cat, a slice of Bread and Butter* akara pẹlu ẹkọ &c. nipa iwasu ti mo nwi, o la itumọ imọlẹ fun wa, a si gbadun rẹ de gere ki Ọlọrun ko ran ijọ yi lọwọ *Amin.*

### ARA ODO IFẸ.

A dupẹ lọwọ Iya Ẹgbẹ Safu Aramide, ara Odo Ifẹ ọmọ luwabı, aya Ọgbẹni I. S. Ogini Johnson, afinju ọmọ Ileṣa, fun inawo ti o ṣe nigbati wọn ko si ile titun; abusi Oluwa o.

BUBUYEH

---

### A JAJA J'AJA.

Akiyesi kan ti o wa ninu *Wire* Ọjọ Jimọ (*Reuters Telegrams*) to jade ni *Wednesday* ọsẹ yi sọ pe Ọba *King* ti yan Ọgbẹni Sir Greame Thomson, K.C.B. ti o ti nṣe Gomina British Guiana ri, ni Gomina Nigeria.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

CATHOLIC.

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbọgbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)

MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

ANGLICAN

| *Time.* | | *Preacher.* |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church, | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | The Curate |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | do. | Mr. C. W. Wakeman |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Bro. J. Majek. Akinloye |
| 6.30 p.m. | | Bro. C. A. Kasumu |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | |
| 6.30 p.m. | | |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. H. Ogunro |
| 6.30 p.m. | do. | |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. L. R. Potts-Johnson |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | do | Bro. D. A. Ogunbiyi |
| | Williams' Memorial Wesleyan (Ebute Mẹta) | |
| 10.30 a.m. | | Bro. S. O. Stowe |
| 7 p.m. | | Bro. J. C. Lewis Lisk |

AFRICAN

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. Supt. D A Hughes |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | |
| 6 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. I. O. Oyekunle |
| 6.30 p.m | do. | Primate J. S. Williams |
| 9 a.m. | Zion | Bro. L. Randall |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. A. Abọyade-Cole |
| 9 a.m | Salem Church (Ebute Mẹta) | Rev. E. David-Ṣodẹinde |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. M. T. Akinṣọwọn |
| 9 a.m. | Bethlehem Church (Ebute Mẹta) | Rev. E. David-Ṣodẹinde |
| 4 p.m. | | Bro. J. E. Ṣowọnọla |

| | | |
|---|---|---|
| 10. a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Williams |
| 7 p.m. | do. | Bro. T. J. A. Green |

BAPTIST

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ebenezer | |
| 6.30 p.m. | | |
| 9 a.m. | Ararọmi | |
| 6 p.m. | | |

ISHOLARIAN.

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | The Founder |
| 7 p.m. | | do. |

EPISCOPAL

9 a.m. & 4 p.m. Patriarch J. G. Campbell

AHMADIA

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Central Mosque, Arọlọya Street.)

ZION CONGREGATIONAL

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens |
| 7 p.m. | do. | do. |

ARMY

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. Jones and the cadets.
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, J. P. A. Taylor

UNITARIAN

| | | |
|---|---|---|
| 10 a.m. | The Minister. | (Arapa Hall) |
| 6.30 p.m. | do. | 21, Williams Street |

AFRICAN FAITHIST KOSMON

5 p.m. 8, Shitta Street. Bro. A. Gbogboade

---

## IGBẸ L'OWO WÀ.

### EKO.

Bi òwò Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti kusi li ọsẹ yi leyi:—

EKURỌ

£16 10 fun *ton* kan.

EPO.

£27 0 fun *ton* kan.

COCOA.

£25—£27 fun *ton* kan.

---

### KANO.

GROUND NUT.

£15 fun *ton* kan.

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo :—Otutu orịṣiriṣi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."




A HEALING CREAM

# Mentholatum

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.

**THE MENTHOLATUM COMPANY LTD.,**
**SLOUGH, ENGLAND.**

*Over 16 million jars sold last year.*

## *Electric Novelties.*

MARVELLOUS BARGAINS.

Mr. M. Sadiku has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc, too numerous to mention.

And also undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

He has also in stock louder bells complete with wire and Salamonical ready for connections. Please call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos and make your selection.

*P.O. Box 378.*

## *Cheap! Cheap!! Cheap!!!*

THE BEST QUALITY OF TAILORS' TRIMMINGS AND ASSORTED TUSSORES IN STOCK

*As Follows* :—Italians, Silesians, Canvas, Sewing Threads, Silk Twist, Crayons, Coat and Trousers Buttons, and Tussores—all in assorted colours, Black Waddind, Brass and White Metal Buttons and Buckles, Dean's Tape Rules, and Best Trimmer Scissores also in stock.

All are of moderate prices.

Orders of other countries from £2 upwards are post free.

*Make hay while the sun shine.*

For further informations please applp to :—

D. O. Adeniga, The Famous Tailor
The direct "Duro T'Oluwa"
23–25, Laveni Street,
Lagos, Nigeria.
(Near the late Mr. Adeshigbin's House)
*The popular trader in Singer Sewing Machine.*

COME! COME!! COME!!!

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts likẹ Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same,* if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

## White's Golden Male Tonic

*(NATIVE)*

(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos*

Packing & Postage 2/6. extra.

SHAKE THE BOTTLE.

## AREMỌ FUN ỌKỌNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki je ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkọnrin ma lo igo mejimeji lošoşu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price ten shillings (10/- per bottle).

## Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!

*Purer than Sugar, Sweeter than Sugar, Cheaper than Sugar and more economical than Sugar.*

Try it in your Cup of Tea Coaca, Coffee or in your Oats or Paps, you run no risk.

Saccharine is absolutely harmless even to the most delicate system ; it is very good for young and old, it is now in use in many homes. "A boon to those who do not take Sugar and to travellers." If you are in doubt consult your physician.

1 Bottle of 600 Tablets for 1/3d.
1 ,, ,, 500 ,, ,, 1/-

*Good Bargains.*

Apply to the Manager :—

APALARA STORE.
72, Great Bridge Street
Ẹnu-owa

P.O. Box 772,
Lagos, Nigeria.

### KERẸ O!

Ọgbẹni M. Winnet Macaulay, ti Ita Oju-oto l'Eko, ( 32, *Vincent Street* ) bẹrẹ isẹ Ẹrọ Alọgi; Ẹrọ na si ni agbara Ẹṣin mẹfa. Bi idan ni Ẹrọ yi fi nlọ Igbado; ẹnikeji o sekọ ni o, o ṣagita ni o, re ḍanwo owo rẹ ko tani lara, ẹ tete mu Agbado nyin tọ lọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, ( l'ebute Olowu ) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, ( l'Anikantamọ ) l'Eko.

O nta Iworo ( Golu ) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. Pereira's, Şẹtẹolu Compound, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance Make a call.

### Coffin ! Coffin !! Coffin !!!

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop 40, Campbell Street, Lagos.

PAUL I. SAMUEL,
*Builder & Contractor.*
Residence and Office 72, Igbosere Road
Lagos.

### Ask From Kaduna Stores.

Everything for Bicycles, Motors, and Gramophones. Newly arrived Gramophones and Zonophones, at cheapest prices as follows :—

£1. 10s. od., £1 15s. od. to £2. 0. 0.

We also stock special Louder Gramophone needles ; these needles play four-records at one time.

Yoruba and English reccords of the latest amusing time.

For Particulars apply to the Manager,

S. A. CLAY
No. 79, Ọdunfa Street, or
1, Macaulay Street,
Lagos.

Cable Address :—
"Steinafrik" HAMBURG

### E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18,
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

### KERE O!

Iya-afin Mrs. Beckley ngu Akara didun ( *Cake* ) ta nile rẹ, ni 53, Opoponla, ō gbeyawo ni o, rē yan tirẹ nibẹ ; o sami fun ọmọ ni o, rē yan tirẹ nibẹ ; o tọrọ ọmọ ni o, re yan tirẹ nibẹ.

Ọpọka-ọyọku ni owo rẹ.

# A. Kessler,

*THE INDENT HOUSE*

FOR ALL GOODS FOR THE WEST AFRICAN MARKET

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

---

COME AND TRY ME!

FOR THE CONOISSEUR

## Crystall Beer Per Case

**33s.**

## Genuine Pilsener Urguell

**Per Case**

**39s. 6d.**

*BREWED IN PILSEN*

AND THE

## Padlock Brand Beer

*48 FULL-SIZED BOTTLES.*

**Only**

**40s.**

Ẹniti ko ba wa ẹran rẹ a bi obukọ.

---

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, E
Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati orișirișí arun ni
ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

A nta Egbogi yi ni Ṣabu Egbogi Ọgbẹni Vic
White, 41, Offin Road, Lagos.

---

### WO'BI ẸNIKEJI,

Oniruru Posi li o wa fun tita; lọdọ P
I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun m
abọ titi de Pọun mejila ṣile mejila. E
ri wọn ra ni 40, Campbell Street,
Ile-isin Ṣọṣi Ebenezer; ati ni No.
Igboṣere Road, nitosi *King's College.*

---

WHITE'S

### WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the b
in such a way, that the regular user is able to
many times the usual amount of Brainwork t
he used to do, before using it. For Brainwork
and those who have examinations to pass, it
boon.

Made and sold only by **SAMUEL VICTOR WHITE E**

41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2½
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1½

**N.B.**—*Scholars should not be without it.*

---

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile
awọn ti o nfi iwe ṣișẹ ati gbogbo awọn ti o
lati lọ fun idanwo.

*Ibã şe ọmọde tabi agbalagba.*

*Dose* :—For adults, Two Desertspoonfuls
youths, One Desertspoonful, 3 time
day after food.

*Akajuwe* :—Fun agbalagba, Ṣibi ti a fi njẹ
meji-meji, fun ọdọmọde, Ṣibi ko
lẹmẹta lojumọ lẹhin ọnjẹ.

---

When replying advertise
please mention *Eko Akete.*

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY
ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET LAGOS, WRITER AND LECTURER